# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 80 SATURDAY, JAN. 19, 1924. Fourpence.

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Bends of all Kinds, Clay and Brier Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano Padlocks, Beads, etc., etc., etc."

**Circulation 1,000 Copies Weekly.**

ẸGBẸRUN IWE-IROHIN YI LA NTẸ LỌSỌSẸ.

N. V. HANDLEMAATSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWON ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode-Lalu, *Leti Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.





In Awọn Oyinbo Onisowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni HerbSTA Nos. 1-4 t'oiwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo o ti fihan ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

...ọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranse ...a tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

...ọn Oyinbo yi nṣe orișirișì Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranṣẹ *Cement* ...nu kikọle to nipọn, ati ẹja abomafọ ati orișirișì ọja.

...un Ile awọn Oyinbọ yi ṣi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn ...SIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

VERSITY OF IBADA... BADA... NIGERIA
KENNET...



## J. C. VAUGHAN

...ec... Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ...ikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

... ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ... tita di oni.

...RI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu ...ọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

E LIBRA...
...ARY:
00 PM A...

---

## B. O. Joseph

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**
**Sundries.**
**Hardware.**
**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

---

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG.

## E. H. STEIN & C...

HAMBURG, Neurwall 16/...
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for

English and Continental Goods

and

PRODUCE

Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Mari... Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store

---

ẸNIKẸJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya ... Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọy... ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Stre... l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

---

# BULL WEST AFRICAN LINE, Inc.

AWỌN ỌLỌKỌ TI IJỌBA AMẸRIKA

Ọkọ elefi awọn Oyinbo wọnyi nko ero ati ẹru ni Iwọ Orun Afrika, ni oşoş... ero lọ si ilu Amẹrika ati awọn ilu miran pẹlu. Ọkọ wọn yara, owo rọ ni ny... Ẹnyin ero, ẹnyin onişowo Obi, Koko, Ekurọ ati Epo, ẹ lọ ke si aşoju awọn Ọ... Oke Pẹtẹsi ile *Colonial Bank*, ni Ẹhin Igbẹti, Eko.

...LE
...treet
...sire
...st
...ing

---

# ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" ni Panu-kikọle ... Iṣọ lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọw... lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja ... awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja ... Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney ... (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati F...

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

### Ẹ JAJA J'AJA.

Ọgbẹni D. A. Ọbasa ti Ibadan bẹrẹ işẹ Iwe-irohin rẹ ni lọlọyi eyiti a ti sọrọ nipa rẹ lọjọ to ti pẹ; oruko ti o sọ Iwe-irohin na ni *Yoruba News* Irohin Yoruba. Ẹ ku a-m'ori-bọ ọ!

### CHARLIE, A GBADUN RẸ.

A ki Ọgbẹni Charles Ọbafẹmi kabọ Ilu Oyinbo ti o ti lọ tun kikọ işẹ *Lawyer*; Ọgbẹni na ba Ọkọ *German* ti a npe ni *Wahehe* eyiti itumọ rẹ jẹ "B'a a ku işe o tan" (*Here we are again*) de ni ọjọ ọsẹ to kọja, o ti di Lọya faufau ni abọ rẹ. O wa ni Pẹtẹsi kan leti ọgba Santana. Ẹ ku ide o.

### IYA NI WURA!

Ọgbẹni wa J. H. Doherty lọ bẹ orori Iya rẹ wo ni Ilu Ijero lọsẹ yi; yio si gba to ọjọ melokan ki o to pada bọ wa sile; a gbọ pe ọrẹ rẹ Ọgbẹni Karimu Ijalẹ ti Isalẹgangan ba lọ pẹlu.

### ỌFẸ NI T'ẸKUN.

Inu wa dun lati jihin pe Ọgbẹni wa Herbert Macaulay (Kiniun Onibudo) ti o ti fẹ si diẹ lẹnu ọsẹ to kọja ti ri alafia nisinsinyi, o si ti nyi kiri ka'di bi oriki Ogunmọla.

### LAWYER IMALE MBỌ WA'LE. Ẹ FARABALẸ.

A gbọ pe a o gba Ọgbẹni Lawal Ibidunni Augusto si awo *Lawyer* ni ọjọ 28 oşu yi, Ilu Ọba, ati pe yio si bọ wa'le ninu oşu *March* ọdunni. Ki Baba f'ẹmi kẹ wa lati fi ayọ ki ọrẹ wa na kabọ nigbati o ba de.

### ABỌ O, AKỌWE KỌ WURA.

Ọgbẹni George I. Phillips Akọwe Ile Iwe Giga (*C. M. S. Grammar School*) ti ilẹ yi pada bọ wa'le lati Abẹokuta nibiti o ti gba isinmi lọ niwọn oşu kan sẹhin, abọ o, ara Abẹ-olumọ.

### IJỌ ELETO ỌMỌ IBILẸ NGBILẸ.

A gbọ wipe Ijọ yi ti ni Ẹka kan ni Ibadan ni Oke Alawọ, ati pe nwọn si ti fi ipilẹ Ile Ọlọrun wọn lelẹ nibẹ. A gbọ wipe nwọn fẹ fi Idipilẹ Ile (*Foundation Stone*) Ọlọrun na lelẹ ni ọjọ *Saturday 19th January* ni Ibadan. Aluta Oyekunle ti Ijọ yi ni yio si şe isin na. Ẹ ku işẹ o ẹnyin Ijọ Eleto, ọwọ a ka o.

"Emi yio si sọ nyin di apẹja enia."

### GBERE, ADAJỌ TO M'ỌYI, TO M'ẸYẸ.

Işẹ gbe wa lọ si Kotu Ebute Mẹta ni Alaruba (*Wednesday*) ọsẹ yi, bi nwọn ti mba Ẹjọ lọ, bẹni a mu obinrin Hausa kan to fẹ lọ w'ọmi wa siwaju Adajọ lati fi sun pe o fẹ pa ara rẹ; ọpẹlọpẹ awọn Ọlọpa meji kan ni ko jẹ ki obinrin yi rì nigbati o kan lu omi; lẹhin igbati baba obinrin na ni on yio şe itọju rẹ, Adajọ fi i silẹ, o si sọ fun baba rẹ pe on fi eyi fã leti, ati pe bi o ba tun şe bẹ nijọ miran, ẹwọn idi rẹ yio gun fun ọdun mẹta.

Lẹhin eyi ni Adajọ na Ọgbẹni H. A. Young K.C. wa pe awọn Ọlọpa mejeji na J. F. Kumuyi *P.C. 441* Ẹgbẹ "C" ati Ọjẹdele Oyeyẹmi *P.C. 542* Ẹgbẹ "C" duro sarin Kotu o si yin wọn fun iwa akọni ti nwọn hu lati gba ẹmi ọmo[illegible]

Hausa na la, o si ni on yio rohin işẹ wọn na fun Oyinbo Ọga wọn l'Eko, ki o ba le wu wọn lori.

Ọgbẹni Young, Adajọ ni lọrun, a bẹ'ri o. !!!

### KILARI YI. ?

A gbọ pe ni *Saturday* ọsẹ to kọja, ogunlọgọ awọn Ẹlẹwọn to wa ni Ikoyi, da bo awọn "Dẹrẹba" wọn pẹlu ọgọ, igi, ati kumọ ti nwọn fi lu wọn ni atupa-moku ; ati pe bikosi ti awọn Ṣọja ati awọn Abişokoto-pọnbe ti a tara ran lọ la wọn ni, bilisi iba ya.

### KINI ẸMI NYIN ?

Ni *Thursday* ọsẹ yi, bi awọn ọdọmọkọnrin meji kan ti nwọn jẹ Gbẹna-gbẹna ni Ọgba Iṣẹ Ilu (*P.W.D.*) nibi, ti şiwọ işẹ ti nwọn si ba ara wọn dimu nibi kan, bẹni ekinni ru ekeji bọ'lẹ, ti a ko si fi gbọ ẹmi lẹnu ẹniti a gbe şanlẹ yi mọ lẹsẹkanna; ọrọ na ti di ti awọn Ọpa Ọba nisinsinyi.

### ILE LO LỌ.

A ba Ọgbẹni Alfred A. Daniel ti No. 38, Evans Street, (Odo Oluşi) Akọwe ni Ile Owo awọn Oyinbo G. B. Ollivant ni'lẹ yi kẹdun ọfọ to şẹ ẹ nipa iku iya rẹ ni Ake, Abẹokuta, ni ọsẹ tokọja. Ẹhin iya a dara o.

---

### ALHAJI ABUDU SALAMI S. DANMEGORO KUDUS.

*Mo gbadun rẹ Ọlọrun lo fi ẹ şe ki işe Enia.*

A gbọ wipe ni ọjọ *Wednesday 31st October* 1923 Iyawo Alhaji A. S. S. Danmegoro şe Wolimọ Kewu Alkuran ti o ke pari. Orukọ Iyawo Alhaji na a ma jẹ Nusirato Labisi Alakẹ Mọlake Majẹkodunmi, Iyawo Alhaji na gbọ ẹkọ pupọ, ki işe iru awọn ọmọ ti nwọn nbi nisẹnyin ti nwọn ko ni ẹkọ rara. Itiju ọmọ na o fẹ ju ti Aka lọ. O si ni iwa rere. Ọmọ na si yayi de gere. Oluwa ko fun ọ ni ọmọkunrin ati ọmọbirin anfani fun ọkọ rẹ. Baba Iyawo Alhaji na a ma jẹ Yusufu Laşẹyẹ Majẹkodunmi, aburo ọlọla J. B. Majẹkodunmi ọtun gbogbo Ẹgba Abẹokuta (*The honourable I. B. Majẹkodunmi Ọtun of all Egbas.*) Owo ti Baba Iy... ati ẹgbọn rẹ ọlọla J. B. Majẹkodunmi ati ... awọn ẹbi wọn yoku, o pọ pupọ, iyin ko to afojuba iru inawo ti nwọn şe leri ọmọ wọn ti wọn si... ni Iyawo fun Ọkọ, nwọn ko ti şe iru rẹ ri n... Abẹokuta ti ki işe irọ. Adupẹ pupọ lọdọ Bab... Iyawo na ati ẹgbon rẹ pẹlu, ati gbogbo awọn enia wọn yoku. Ọlọrun Alanu ko fi ałubarik... sinu owo wọn, Ọlọrun ko fun Iyawo ni ọm... anfani. Amin.

O tun han fun wa gbangba wipe Alhaji Abu... Salami, S Danmegoro Kudus Ọkọ Iyawo na, o na kasinkan owo şile, nigbati o di *Saturday 3rd November* 1923, Alhaji Donmegoro, kọwe ranşẹ si gbogbo awọn Alhaji Abẹokuta lati wa ba on dupẹ fun Oluwa, fun Igbeyawo rẹ, gbogbo awọn Alhaji na si wa ni ọjọ *Saturday* na gẹgẹ bi ... ti pe wọn ni alai ko da ẹnikan si, Alhaji Danmegoro si fi orişirişi onjẹ su wọn. Awọn Alhaji na şe ọpọlọpọ adura fun Ọkọ Iyawo na, Olukuluku awọn Alhaji na lo yọ lọ de le, fun iyalẹnu wọn wipe enia lo şe iru inawo nla nla bayi, Oluwa Alanu ko b'aşiri Alhaji Danmegoro, ko si fun ni ọpọlọpọ ọmọ kunrin ati Ọbinrin anfani. Amin. Ọkẹ aimoye awọn ẹlomiran tun wa si bẹ ti nwọn tun jẹ ajẹsu onjẹ. Orukọ diẹ ninu awọn Alhaji Abẹokuta ti o wa sibi apejọ na ni yi :—

Alhaji Raji Agọowu, Alhaji Raji Itoko, Alhaji Yushawu Kanyinde, Alhaji Sakariyawo Sunmọnu, Alhaji Abudu Wahabi, Alhaji Abudu Lasisi Kudus.

Alhaji Danmegoro Enia-şoro, de lati Abẹokuta si Eko ni *Saturday 10th November* 1923. O si tun sọ wipe on şe inawo Iyawo on nibi ti nwọn bi on si ni Abẹokuta, o tun ku ibi ti wọn tọ on dagba iyẹn Eko, *Lagos.*

Alhaji A. S. S. Danmegoro Kudus pe gbogbo awọn Alhaji Eko ni *Sunday 2nd December* 1923, lati tun ba on tun ọpẹ da fun Oluwa fun Igbeyawo ti on şe ni Abẹokuta, gbogbo awọn Alhaji wa si ile rẹ ni 104, Alakoro Street Lagos, ni agogo mẹsan abọ. Alhaji Danmegoro fi orişirişi onjẹ suwọn, nwọn si dupẹ pupọ fun Oluwa fun ọpọlọpọ inawo nla ti Alhaji na şe, ti ẹnikẹni si ri wipe o nawo ni ti ka-sinkan.

Inu gbogbo awọn Alhaji ti nwọn wa sibẹ dun pupọ, ti nwọn sọ wipe nwọn fẹ ki Alhaji Asani ọmọ Imam Onigbanjo ko şe adura fun Alhaji Danmegoro, o sişẹ adura na fun. Ọpọlọpọ ọrọ rere ni awọn Alhaji na sọ nibẹ, şugbọn bi a ba sọ wipe ki a sọ gbogbo rẹ tan, iwe ọsẹ kan yi on nikan ni o ma jẹ, nitorina ni aşe fi mọ gẹgẹ bayi. Gbogbo ẹnyin Alhaji ti ẹ lọ si ibi Iyawo Alhaji Danmegoro, Ọlọrun ko bo aşiri nyin. Amin. Ọlọrun ko fi rere kari. Amin. Orukọ diẹ ninu awọn Alhaji Eko ti nwọn wa si ibi Iyawo na ni yi :—

1. Alhaji Abudu Salami Oke-ārin, ati ọmọ rẹ ti o mu lọ si *Mecca* pẹlu, 2. Alhaji Asani Onigbanjo, 3. Alhaji Sakariyawo Olori, 4. Alhaji J. G. Bakari Ọtun, 5. Alhaji Shittu Alaka, 6. Alhaji Sule Bakare, 7. Alhaji Buraimọ Uthman.

Nigbati o tun di agogo marun abọ, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Abẹokuta ti nwọn jẹ gbajumọ awọn tun wa si ibi Iyawo Alhaji Danmegoro na, gẹgẹ bi o ti pe wọn, o na ka-sinkan owo fun wọn, inu gbogbo awọn ẹgbẹ na dun pupọ fun inawo nla nlā ti Alhaji na ṣe, gbogbo awọn ẹgbẹ gbajumọ wa ṣe ọpọlọpọ adura rere fun. Oruko ẹgbẹ na a ma jẹ "*Egba Auxiliary Society.*" Ọ̀ọ diẹ ti awọn ẹgbẹ na sọ wa ninu iwe.

Sanni Adeyẹmi Danmegoro Ọtun ẹgba Oke-ọna, Abẹokuta, Baba Alhaji Abudu Salami I. Danmegoro, o na ka-sinkan owo nigbati o nṣe Iyawo fun ọmọ rẹ, Alhaji Danmegoro, a gbọ wipe ni'jọ *Wednesday 31st October* 1923, nigbati Iyawo Alhaji na ṣe Wolimọ ti o de ile ọkọ rẹ ni dede agogo meji abọ ọsan, Baba Alhaji Danmegoro, nṣe ni oro nfun owo ṣile bi ẹni da omi.

Nigbati o tun di *Friday 9th November* 1923. Sanni Adeyẹmi Danmegoro Ọtun Oke-ona o tun gbe Iyawo fun aburo Alhaji ọkunrin Bisiriyu S. Danmegoro. Baba Alhaji Ọlọrun ko ran ọ lọwọ. Gbogbo owo ti o na si ori awọn ọmọ rẹ, Alhaji Abudu Salami S. Danmegoro ati Bisiriyu S. Danmegoro. Oluwa ko fi ọpọlọpọ dipo rẹ fun ọ. Amin. Oluwa ko si fun awọn Iyawo na ni ọkunrin ati obinrin anfani. Amin.

ATOLUGBOKUN.

**FRIENDS and COUNTRYMEN,**

**LET US SEIZE THE OPPORTUNITY OF THE DAY.**

Become a certified Medical Herbalist and learn how to alleviate human suffering by the skilful use of

***NON-POISONOUS HERBAL REMEDIES.***

The British College of Herbal Medicine of Bolton, England, prepares students to qualify as certified HERBALISTS by studying their Correspondence Course of Lessons.

For full particulars, apply to the Official Representative of the College :—

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos, Nigeria, W.A.

**Remember that :—**

***The more you know, the more you know how little you know.***

## *Open Letters.*

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 43.**

TO THE HONOURABLES

J. EGERTON SHYNGLE, ERIC. O. MOORE AND C. C. ADENIYI-JONES.

*Members of The Legislative Council, Lagos, Nigeria.*

Gentlemen of The "Parliament of Nigeria,"

One of the very urgent questions which your Electorate would urge on you to lose no time in asking the Government at the Second Session of the above Council which has been fixed by Proclamation, for the 11th *Proximo* is the alleged *shabby treatment* to which some African Government *Employes* are said to be usually subjected in the matter of *Accomodation* whenever they are asked to take up duties in places other than Lagos in the Leeward, either temporarily or permanently by transfer.

More often than not, it is reported that in some cases, African Clerks sent abroad as previously stated, "On His Majesty's Service" are generally put at great pains in finding comfortable shelter in which to lay their heads: in other respects, it is said, they are obliged to make the best of a bad job by contenting themselves to sleep in *open air*, with scarcely any awning: again, it is given out, that sometimes some of these clerks are only too glad to share quarters with cattle ! ! ! until they are fortunate enough either to secure lodgings on hire out of pocket—so I am told—or to be at the mercy of a casual friend, a chance fellow-countryman if you please, who will feel disposed to come to their rescue and thus save them from the ravages of the weather.

Moreover I am given to understand that in the case of Europeans who are similarly sent out, *ample provisions* are provided, in the shape of the erection of bush-houses where there are no quarters originally, to say nothing of the comforts in which they are said to be rolling; this, in striking contrast to the lot of their fellow-coloured colleagues forsooth.

Quite recently the sad case of Mr. Atitebi of the Treasury (Lagos) who was sent to Port-Harcourt on duty and who, it is reported to me, owing to the absence of an accomodation, over there was obliged,—so rumour says—to find shelter in a shanty for few days which act, I am told, resulted in his being attacked with Pneumonia to which he succumbed consequent on the alleged exposure.

You, Gentlemen, I doubt not, will leave no stone unturned in investigating the various issues raised in this letter, and so save the country from disgraceful anomaly regarding this alleged treatment of some of the African members of the public service.

The country awaits your action thereon with undiminished confidence.

EKO AKETE

**EKO AKETE.**
EKO, SATURDAY, JANUARY 19, 1924.

## ẸNIT'O BAJẸ TI BAJẸ NA, ẸNIT'O MA BALUMỌ LOKU !!!

Nigbati a sọ ninu Iwe-irohin wa ti ọsẹ tokọja, pe a o sọ kasi-nkan ọrọ lẹhin igbati ọrọ Alaji Salusi ti Latiaji ba pari ni Kotu—a si ti ri gẹgẹbi o ti pari si—kiṣe ifẹ inu wa lati tẹ ẹniti o ti ṣubu lulẹ wẹ̄n-wẹ̄n, itumọ eyi ni pe lẹhin igbati Adajọ kekere ti "da sẹria fun Alaji na, nipa pe ki o san ogun pọnun (£20) s'apo Ọba a-ko si nipo ẹniti o ma ṣe "jinginni, o dun mọ mi" si Alaji yi. A si kilọ fun awọn ẹlomiran ẹ̀wẹ̀, boya ti nwọn ni inu didun lati ṣe yẹ̀gẹ̀dẹ̀ si Alaji yi, ki nwọn dakun ṣiṣe bẹ: "Makan-makan ṣa ni oye nkan" "Agutan pọ̀po a bi onde l'ọrun olukaluku a-bi ti ẹ lara;" aro ẹniti o ṣa yọ ni enia nrẹ, olukuluku wa lo so tirẹ mọ ipakọ eyi mu ni ranti orukọ ẹnikan ti o ni on nịẹ "Ma f'ọrun yọ mi, gbogbo wa lo jọ nlọ." Nitorina ọrọ yẹyẹ kọ ni a fẹ tun sọ si ẹjọ na.

Solomon Ọba to bori Ọba sọ ninu Iwe rẹ kan ni Bibeli pe "Ifẹ lagbara ju iku lọ," gasikiya leyi: o ṣoro ki obinrin kan ibaṣe Wundia, tabi Adelebọ fi tifẹ-tifẹ fẹ ẹniti ko ni ifẹ rẹ ti o to dudu ori ekanna; o jẹ aṣiṣe awọn obi miran lati fi ipa jẹki ọmọbinrin wọn fẹ ẹniti awọn fẹ—boya ojo owo ti rọ lati ọdọ ọkọnrin na si wọn ni lalaijẹpe ọmọbinrin wọn na ran wọn ni ṣẹ; iru nkan bayi wọpọ ni'lẹ wa pãpã ni ilẹ Yoruba ni igba lailai a si ro pe bá'ãbá rẹ ṣi ku sibẹ nisinsinyi; eyini ni ki awọn obi ọdọmọkọnrin kan ma ṣe ana ọ̀lọ́-ọmọbinrin ti a ṣẹṣẹ npọn lẹhin: ki nwọn mã ṣe iṣẹ ana, titi ọmọdebinrin na yio fi dagba ti yio to ẹni-ọkọ pẹlu ọmọ wọn ọkọnrin, ti awọn obi na yio fi "ṣíkà" alukawani wọn fun awọn obi ọmọde'binrin yi nipa jijẹ ẹ̀jẹ́ wọn bi ana, ti a o si gbeyawo fun awọn mejeji. Ẹ o kiyesi pe ifẹ kan ko si tãrà lati ọdọ ọmọbinrin yẹn wa, lẹhin didi wundia rẹ si ọdọmọkọnrin yi, awọn obi wọn "lo pa lo si sin;" irufẹ ọna bayi le wọ ode igba lailai; ṣugbọn gẹgẹ bi o ti jẹ pe ewe isinsinyi ni a fi nwo arun isinsinyi, irufẹ ọna bẹ kò múrọ mọ ni ode t'oni; nitorina ni a ṣe nri ikunsinu ati asọ larin awọn ọmọ obi miran papa awọn ọmọbinrin ti obi wọn ba fi irufẹ iwa yi lọ. A ti mo ile ti o ti fọ ti aya gba Ẹpẹtẹdo, ti ọkọ si gba Oyingbo, nitoripe ni a-tete-kọṣe, nṣe ni obi ọmọbinrin fi agbara mu ọmọ rẹ fẹ ọkọnrin ti ẹni ọmọ na ko fẹ; a ko sọ pe ija ki si larin awọn ọkọnrin ati obinrin ti nwọn ti'lẹ fẹ ara won ṣugbọn bi a ka leni, leji, a o ri pe ikorira wa ni ọkan pupọ ju ekeji lọ. Irufẹ ọna fifi ipa fẹ Obinrin ti ko ni ifẹ ẹni, losun Alaji Salusi si ijọngbọn ọsẹ tokọja bi o ti lẹjẹpe a ko gbọ pe baba ọmọ na f'ori fa ninu "abọ" ode Kotu ti Alaji na bọ, sibẹ igbagbọ wa nipe atisu'ke ko ṣẹhin lakuregbe–fifi ipa mu Awawu *Miss* Thomas lati jẹ aya Alaji Salusi, ko ṣẹhin Ọgbẹni Abudu Thomas baba ọmọdan na; a si dupẹ pe Ọgbẹni wa *Dr*. Oguntọla Ṣapara I.S.O. sọ ni asọye ni Kotu ni *Jimoh* ọsẹ tokọja pe awọn Imale gbagbọ pe Obi lè ṣe ọmọ rẹ̀ bi o ti fẹ, papa nipa fifi-ọmọlọkọ ti pẹkẹ ko ni mi, *Dr*. Ṣapara sọ pe iru eyi le ṣeṣe ni ilu ti o jẹ pe Isin Mọmọdu ni awọn Alagbara Ilu na ntẹle, gẹgẹ bi ilu Tatambulu; o ni ṣugbọn labẹ asia Gẹsi ọmọ George Ọba *King* ni gbogbo wa jẹ, kosi si ẹniti olè sé ni mọ'le nipa—gẹgẹ bi ati da Alaji Salusi yi lẹbi pe o sè Awawu mọ'le ni ọna ti o lodi s'ofin—ki tẹ́tẹ́ ofin má jẹ oluwarẹ iba ga kọ to Erin ki ganaku rẹ̀ to Ẹfọn.

Ẹwọn ọdun meji ni ofin Amuniṣuye (*Criminal Code*) sọpe ki a ju ẹniti o ba jẹbi irufẹ ọrọ bi ti Alaji Salusi yi si, ṣugbọn a dupẹ pe Adajọ kekere na fi "Sẹria" to da nipa pe ki o sanwo, ṣe Ekinni kẹbẹ fun u.

Ki awọn Imale ọlọkan bi ti Alaji yi maṣe jẹ ki a ṣe Ẹkẹta Ajẹ-Ajẹtan fun wọn ò, ki ògo mã bã de Ile Iku rẹ̀!!!

## ENIA ŞORO!

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Orişirişi enia li o mbẹ li ode aiye; bi a ko ti le fẹ ẹni rere kù, bẹni arigid'enia pọ to wobu. Ọlowo mbẹ, talika mbẹ, alãnu mbẹ, ọdaju mbẹ, ọgbọn mbẹ, omugọ mbẹ, oniwa-pele, onijagidijagan, onitiju, alailojuti, onirẹle, agberaga, olotito, ole, abi'ko, ako'gbọn: ani oniruru ati oniwakiwa enia gbogbo li o pọ ninu aiye.

Nitotọ, enia yatọ si Malẹka: iba si şe wipe gbogbo ẹda ti o wa li aiye li o jẹ ẹni mimọ, boya ki ba ti si Mọşalaşi tabi Şọşi kanşoşo li arin wa. A da Mọşalaşi ati Şọşi silẹ nitori ki a le ri aye kọ wa ni ohun ti Ọlọrun fẹ, ati eyiti O kọ—şugbọn sibẹsibẹ, awọn ọmọ Anabi Adamọ fẹ okunkun ju imọlẹ lọ.

Nigbati Alufã, omọ onibi-niran, ti o ngbe ile ọfẹ, ti o si ngba owo daradara li oşoşu, ti o nhu iwa ko-jọ-ole, ko-jọ-afowọra, titi nwọn fi nyọ ọ kuro ninu işẹ Alufã bi ẹni yọ jiga, a ko şai mọ nigbana wipe işẹ akanşe adura papa li o de ilẹ yi—ko nşe adura ti ologomugomu.

Gẹgẹ bi Orilẹ-ede, anu ko le şe ki o ma şe ni lati ma ri işubu ọmọ ẹnikeji wa bayi; şugbọn enia dudu melo li o ha mọ wipe ẹtẹ Awo ni ẹtẹ Ọgbẹri. Bi nkan rere ba kan ẹnikan—enia diẹ ni yio gbo, şugbọn jẹ ki o şe nkan buruku, ki o to to işẹju mẹwa, eku ile a ti sọ fun ti oko: bi enia şe aisan diẹ, ọfọ iku rẹ ni nwọn a ma tú kãkiri, bi Ọlọpa ba si jaja mu ẹnikan, tabi ki ọran ẹjọ de ba ẹnikan, dipo ọrọ ikãnu tabi ọro itunu, "Ò pẹ ti o ti nşe, ọwọ tẹ ẹ wayi, mu u "re" ni õ mã gbọ kãkiri. Ẹnikan ko fẹ ilosiwaju, bikoşe işubu ọmọ ẹnikeji rẹ—Enia bi aparo sa ni aiye nfẹ.

Ọtọ ni akowe Ọba, ọtọ ni akọwe onişowo nwijọ pe Oga wọn ko fẹ ire ati ilọsiwaju wọn, alakara ko fẹ ki elomiran din, awọn Oşe'lu (*Politicians*) ijowu ... wọn, arankan ati agabagebe Alufa miran ju Judasi lọ, ẹgbọn pẹlu aburo nja nitori oyè Lemọ..., ọganjọ oru si ni ọsan gangan awọn ẹlomiran.

Danasun... bo nlu ilu, Isobo nşan omele; nkan kan li o m... gbẹhin ijó lamùrín.

Emi ni ti nyin nitotọ.

ATARI AJANAKU.

## ỌMỌ ATIRO TI O NGUN AGERE ỌRỌ LO FẸ GBỌ!!!

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo juba o,

Awon agbalagba lo ma np'owe kan pe, "Iso ni Olokunrun ma nfi dupẹ lọwọ Onişegun" toto o!

Mo toro gafara lọwọ rẹ "Eko Akete" lati mo tani oluware na ninu aiye yi ti o pe ara rẹ ni "Akede Otitọ" ninu "Eko Akete" ti ọsẹ to koja 12/1/24 ti ẹnu rẹ si gba a lati soro ọja ti *Church C.M.S* ni Ajido, ti o si nfẹ lati fẹ ina ija ti o ti pari lailai, nwọn ha bi "Akede Otitọ." yi nibẹ ni tabi nwọn ra a wa si ilu Ajido ni? Ti o ba şe wipe nwon ra a wa ni, tabi o fi ẹsẹ ara rẹ rin wa si Ajido ni, njẹ ki o şọra ki o maşeda rugudu si ilu onilu, "a ki sa de ilu onilu ki a şu arun k'agbọn," bi o ba si jẹ pe a bi Akede Otitọ (ti emi mọ ni Akede *Eke*) yi ni ilu Ajido ni, njẹ ki o lọ sọdọ Iya Ajẹ ti o wa ni Endori (*the whitch at Endor*) ki o ba a ji awọn oku rẹ dide ki o si gbọ itan ija yi lọwọ wọn, ki o to wa fi "àta ré, mọ àta rè" ki on na ki o ma ba joye "arijẹ ninu idaru," ati pe nigbati o ba gbọ itan yi dara dara lẹnu awọn oku rẹ, ti Iya Ajẹ Endori ba ji dide fun tan yio wa ri daju daju pe "Akede *Eke*" ni orukọ on nitotọ gẹgẹ bi mo ti npe e.

Mo ni bi o ba jẹ totọ ni a bi ẹniti a npe ni Akede *Eke* yi ni Ajido, njẹ Iso ni Olokunrun fi ndupe. Ki a tilẹ gba wipe nitotọ ni ija de larin Ọgbẹni ti "Akede" yi pẹlu awọn ijọ rẹ gẹgẹ bi o ti wa nibi gbogbo, ewo lo ba to ohun ti enia ma fi ọwọ rẹ şişẹ tan ti yio si wa fi ẹsẹ rẹ yi i danu, a ko mọ pe Akede *Eke* yi le şe iru rẹ şa o!

Emi ko jade lati şe ẹnu ebu rara, şugbọ mo jade lati fi han gbogbo aiye pe otitọ ko si ninu ọrọ Akede yi, bikoşe "Iso ti Olokunrun fi ndupe," nitori mo tanmã pe, anfani Isin ti Ọgbẹni (ti a sọ isọkuso si lara) yi mu wa si Ajido ni Akede *Eke* yi ati gbogbo awọn ẹgbẹ rẹ njẹ titi di oni oloni. Boya ọmọde ni eniti o pe ara rẹ ni Akede Otitọ yi tabi agba ni emi ko mọ, şugbọn mo fẹ ki o mọ pe bi enia ba fi ibi şu olõre ti o bo epò (*Weeds and bulrushes*) kuro loju ẹni, Ọlọrun yio binu si oluwarẹ lai ati lailai, afi ti o ba tọrọ idariji fun ẹşẹ rẹ.

Awon ti o ro pe o tọ, o si yẹ pe ki isin Ijọ ọmọ Ibilẹ ki o ma gbilẹ kakiri ko ni Ẹmi "Mata omi si mi lara ti ki iwa odo" nwọn si mo pe igbi omi aiye yi le bi agbo Ijọ ọmọ Ibilẹ şubu ni Ajido.

STREET

...ic Address "

UNIVERSITY OF IB



Nitoripe nwọn ko fi rikiṣi bẹrẹ rẹ, ko si si agabagebe ninu isin wọn, eyi daju gbangba ati nipa agbara Ọlọrun Ijọ yi yio gbilẹ lọ siwaju ati siwaju. Aṣẹ! Nitorina ki Akede *Eke* yi ki o maṣe da "luru mọ ṣapà."

O si tun jẹ ohun ti o ti mi loju lati gbọ lati ẹnu Akede yi pe ilọsiwaju Ijọ ti *C.M.S* ti o wa ni Ajido "ko wu ni lori," ni ti emi awọn Ijọ *C.M.S* Ajido nwọn ṣe iba ti agbara wọn le ṣe, emi ko si le ba wọn wi si eyi. Bi ọrọ Akede yi ba jẹ otitọ, njẹ a le bere pe, Ajala tani na ọ!!! bibẹkọ ṣe iṣẹ Ọlọrun ki ṣe ti ẹnikan iṣẹ gbogbo aiye ni, njẹ, a le bere pe nigbati Akede *Eke* yi ri pe iṣẹ rere ti Ọgbẹni kan mu *C.M.S* wa fi lelẹ pe ilọsiwaju rẹ ko wu ni lori, kini Akede *Eke* yi ṣe si i "Emi lo ti ṣe?" gẹgẹ bi aṣa awọn ara oke (mo tọrọ gafara fun eyi) kaka ki Akede yi joko ko ma jẹ anfani ti Ọlọrun ni ki Ọgbẹni yi fi si on lẹnu jẹjẹ ni kọrọ iyara rẹ, ki o si ma fi ibukun fun orukọ Oluwa, ki o si tẹriba fun orukọ Ọgbẹni na, o bẹrẹ si sọrọ alufaṣa ti Ọlọrun yio fi rọjo ibinu gbigbona si i lori.

Bi Akede *Eke* yi ba gbọ ede Egun, ngo sọ fun wipe "Yin-a-yin yọn-ẹn-vi ana yọn ẹn, yin a sọ yin thẹn-vi ana thẹn." Bi a ba ni mọ ọ ọmọran a mọ ọ (*Verb Sap Sapienti*) Mo fẹ ki Akede yi mọ pe, ọrọ alaimore ni on nsọ (*ungrateful effusions*) Bi ẹru ijọ *C.M.S* Ajido ba wọ, ki Akede *Eke* yi ki o jade pẹlu gbogbo imọ rẹ ti o ba ni ki o si lọ tun u ṣe fun alafia gbogbo ẹnia, "A gbe Gàri (*Saddle*) kalẹ ewurẹ nyọju" ẹru baba nla ewurẹ kọ rara!!!

O ma dun mi ti nko mọ ẹniti o pe ara rẹ ni "Akede Otitọ" yi o, ṣugbọn mo gba a ni imọran pe ki o yara ko'gbà si'le, ko ma fi ori ara rẹ jo'na......mo si nfẹ ki o jade si gbangba ki o si sọ bi ọmọ Ajido ni on tabi alejo ki nle wa fọn oguna ṣuṣu le e lori.

Ijọ *African Methodist* ti de si Ajido ni agbara Ọlọrun gẹgẹ bi "Itàkùn ti o ni ki Erin ma g'oke alọ, on na ni yio fi ọja di." Gbogbo awa ọmọ Egun ti o wa ni Ajido ati pẹlu ni yio ma fi iyin fun Ọlọrun ninu Ijọ ọmọ Ibilẹ Ajido pẹlu gbogbo awọn Olorişa ati awọn Imale.

"Eko Akete" Ọwọ rẹ a roke o, ilu Eko yio toro ati gbogbo agbegbe rẹ ati ilu temi papa Ajido, ni Orukọ Oluwa. Aṣẹ.

Emi ni tirẹ nitotọ,

ALỌMA-VI.

---

**STOP PRESS NEWS.**

**Luncheon at Bonanza.**

The Honourable J. Egerton Shyngle (First Lagos Member) entertained to Luncheon Messrs. Clinton and Macauley of the Calabar Bar at The Bonanza, this afternoon

## Thanks for Sympathy

Mr. Jacob O. Thomas and Mrs. A. W. Thomas on behalf of themselves and family beg to tender their sincere thanks to all those who by personal calls, telegrams and gifts expressed sympathy with them in their most lamentable bereavement occasioned by the death of their father and husband, ANDREW WILKINSON THOMAS which took place on Monday 7th, January, 1924.

---

**WESLEYAN HIGH SCHOOL OLD BOYS' ASSOCIATION.**

A General Meeting of the above-named Association will (D.V.) take place on Friday the 25th instant at 5.30 p.m. in the School-Hall.

All Old Boys are to be present.

**Agenda:—**

(1). Presidential Address.

(2). Election of Officers.

Lagos. 16th January, 1924.

---

A ni Aga titun fun yiya ni owo pọ̀. (1½d) kọbọ kan pẹlu abọ pere ni, lọ si ọdọ:—

Ọgbẹni W. O. AJỌṢẸ,
No. 3, Ita Doherty,
Oke Arin,
l'Eko.

---

## IN MEMORIAM.

In loving and affectionate remembrance of our dearly beloved Mother and Grandmother

SUSANAH LAWRENCE

Who has left to resume a happ[illegible] world on the 12th day of January, [illegible]18.

Accross the bridge of death [illegible] love lives yesterday, today, and for everm[illegible]re.

There is one angel that guard[illegible] our loved ones, and that angel is "Mem[illegible]y."

## FACTS AND FIGURES

### OFFENSIVE JOURNALISM.

In these days one does not know what the world is coming to.

The great war which was filled with atrocities and all sorts of brutalities unheard of in history—all garbed up in that pet phrase, viz, *Civilisation*—has lifted the thin veil which, from time to time, had covered a world of gross irreligion and sordid materialism. The ideal "Thou shalt not resist evil," is to-day in the melting pot and the principle "Tit for Tat" has plunged the world into an unusual perturbation No more "live and let live." With individuals as well as nations the strong must always oppress the weak To this state of universal unrest and uncertainties the journalistic world is not an exception. Foul language, with the malicious intention of holding up individuals or groups to ridicule and contempt, has been freely used in columns of newspapers by people who claim to *educate* the public.

Among a thousand and one signs of the present time is the recent libel action brought against Lord Alfred Douglas for publishing an untrue and defamatory writing against Mr. Winston Churchill.

But we are much concerned with conditions in Lagos. A local journal which sprang into existence last year, but which persistent pugnacious attitude and usage of abusive and ridiculous parlance has disgusted all sane readers has just said: "There is no healthy public opinion in Lagos."

It is simply plausible that the very people, through whose mudslinging propensities the town could not progress, should turn round to rejoice in such disgraceful remarks.

Recently, one paper was strongly attacked by another for an alleged vulgar statement that the Resident of the Colony should be compulsorily retired. But the latter contemporary in its review had nothing to offer the public but a lengthy rigmarole more vulgar than the article complained of.

Lagos of to-day, more than ever, wants leaders of good taste and newspapers that would reflect credit on the race. The so-called ignorant mass are not so much at fault as their supposed leaders who, with *presumed intelligence and respectability*, will keep on jumping at one another's throat.

We sincerely wish things will take a better turn.

ADEKANBI·

---

### RESPECT THE KING'S COURT !!!

In the District Court of Ebute-Meta, on Wednesday last, the learned Magistrate His Worship H. A. Young, K.C. whilst on the Bench dispensing justice to all alike, turned out unceremoniously one European probably a litigant, who came to the Court in a dress not befitting the dignity of his Majesty's Tribunal with which views we agree: needless to say the man was immediately shown the door through which he disappeared in the twinkling of an eye.

Hats off to His Worship.


# John Holt & Co.,

*( Liverpool ) Ltd.*

"Flag" Cigarettes

"Elephant" Cycles

Rudge-Whitworth Cycles

Crockery

Enamelware

Dried Fish

Flour

Sulphur

White Lime

Alum

Coal Tar

Paints

Wire Nails

Corrugated Iron

Ridgings

"Pilot" Matches.

**JOHN HOLT & Co. ( L'pool )**

BROAD STREET, LAGOS.

*Telegraphic Address* "EBANI"

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9 30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church The Vicar
6.30 p.m. do. do.
9a.m.—St. Paul's (Breadfruit) Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
6.30 p.m. do.
9 a.m. St. John's (Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Peter's (Alapako) Rt. Rev. Bp. I. Oluwole
6.30 p.m. (In charge)
9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) Rev. S. J. Gansallo
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. A. Leigh
6.30 p.m. do.

WESLEYAN

10.30 a.m. Tinubu Rev. A. N. Cole
7 p.m. do. " do.
10.30 a.m. Ereko " E. K. Ajai-Ajagbe
7 p.m. do. " do.
10.30 a.m. Olowogbowo " S. A. Pearse
7 p.m. do. " E. K. Ajai-Ajagbe
10.30 a.m. Ọbun Eko Bro. Dan. O. Mould
7 p.m. do " E. E. Ajọṣẹ

AFRICAN (COMMUNION)

9 a.m. Jehuvah Shalom Rev. G. A. Oke
7 p.m. do. Bro. Ọlaboye Lalẹyẹ
9 a.m. Erelu " J. H. Lawosn
7 p.m. do. Rev. J. F. Ogunko
9 a.m. Christ Church (Ebute Mẹta) Bro. A. M. Williams
6.30. p.m. do. Rev. J. F. Ogunko
9 a.m. Bethel Rev. Supt. J. S. Williams
6.30 p.m. Rev. E. A. Akiọla
6 a.m. Zion
6.30 p.m. do.
10.30 a.m. African Methodist Bro. W. K. Fafunwa
4.30 p.m. Bro. S. A. Fatolu

FIRST BAPTIST CHURCH

10.30 a.m.
6.30 p.m.
9 a.m. Araromi (Baptist)
6 p.m.

EBENEZER (BAPTIST)

9 a.m.
6.30 p.m.

BROTHERHOOD

7.30 a.m. Ilupesi Resp'table Bro. D. O. Adesanya
7 p.m. Prof. Adeoye Deniga

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service I. A. Shitta
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH. (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

10 a.m. Glover Memorial Hall Capt. A. A. da Costa
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. F. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

### LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọwọ wọnyi ti gba Oja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product,
£15 10—£16 fun *ton* kan

EPO.

£25—£26 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£17—£18 fun *ton* kan bakanna

---

**KANO—COMPETITIVE PRICES**

Ground Nuts £15—£15 2 6 per ton.
Skins 1/9 per lb. Hides 5d per "

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

PRICES ON APPLICATION.

TO

S. I. M. Johnson,
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

**Chairs ! Chairs ! !**
**Chairs ! ! !**

For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,
J. A. OSHODI,
26, ỌBUN-EKO SREET,
LAGOS.

**AGA, AGA, AGA.**

FUN ;YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.
OWO;PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½D.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,
Ọgbẹni J. A. OSHODI,
No. 26, ITA ỌBUN-EKO,
LI EKO.

**The Union Night School.**
FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge, Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor)
For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun g bogbo ọmọ Ile-iwe ati oṣiṣẹ pelupẹlu fun awọn ti o ufẹ lati ṣe idanwo fun iṣẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nko iwe Yoruba nibẹ. A nṣe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday, Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* ( Loke. )

GOOD MARKET.

At H. Campos's Shops, 7, Campbell Street, 2, Faji Market, and 63, Ọdunlami Street, Lagos.

NERVE TONIC.

Moloke Mone A. & B. 6/- & 5/- a bottle.
Bula Matadi 7/- a bottle.

WONDERFUL GONORRHOEA SPECIFIC WITH INSTANT RELIEF, WILL CURE THE MOST OBSTINATE CASES.

Euregon Pillen Pills at 3/6d. a Packet.
Euregon Liquid 4/- a bottle.
Gramophone records 10 ins. & 12 ins. Best Cigars superior quality. Provisions in endless variety.

CASH ONLY.

**Change of Address.**

Mr. Karimu Kotun on behalf of his Firm begs to inform the Public that he is removing their Show-room from No. 20, Porto-Novo Market Street & Broad Street, Lagos, to No. 3, King Docemo Street, Lagos. (Babu Kaman Ala) with effect from the last day of January, 1924, and that all communications intended for him or his Firm from that date should be directed to the latter address.

## A. KESSLER,

7, Labinjo Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
The German Trading House,
Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

FOR SALE

The Typewriter "Perkeo" £9 5 0

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Decent Wristlet Watches sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc,

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite

CHAMPAGNE per case £3 5 0



## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*



## Aworan Alarabara.

A ni Aworan onirum fun [illegible] ti şe ile I eşo. A ni ti tite oku Jesu, ti igbati a da a li ehi iku, ti Onigbale ikebin. A ni ti Adam ati Efa, ti işedale aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ola re, ati nigbati o di erinko; ti obirin ti o fi owo nu ejo, ati ti Oba Talambulu.

A ni [illegible] O [illegible] Iyo-iyo mbe lowo wa fun tita bi wobu, bi o ba fe e ni [illegible] fun o [illegible] fun tita, ko si bi a lonşe won [illegible] lo wa lowo wa, iwo ko le ba wa şowo ko ma jere tire, [illegible] rekoja ala. Bi o ba wa si ile-oja wa "Ka mi, ka mi" ni ohun won, bi o ba fe ja iro wa, rin wa si ile oja wa.

Iye owo won:—3d, [illegible] 6d, 1/- okokan 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d tun mejila.

Ibikibi ti e ba mbe ni Nigeria [illegible] ehin okun kowe şowo yala ni ede Gesi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMEE & BROS,
38, Mobandy [illegible] Street, [illegible]
(*Legbe awon Qnişowo A. J. Tangalakis*)
Idumagbo, Eko.


## KNOW ALL MEN

That I, formerly known as

ISAAC AKINOLA COLE

Builder & Contractor of No. 1, Market Street and 48, Breadfruit Street, Lagos Nigeria, desire to be known, called and addressed from the first day of January 1924 as

ISAAC AKINOLA OGUNMODEDE.

All Transaction, Documents, Papers etc., bearing the first name remain valid.

Dated at Lagos this 24th day of December, 1923.

I. A. COLE

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.